# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàíjíríà.

**Oṣù Kẹsàn, Ọdún 2026**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**OṢÙ KẸSÀN, ỌDÚN 2026**

**À N KỌRIN AGBÁR' ỌLỌ́RUN**

**1. À nkọrin agbára' Ọlọ́run,**
Tó nṣí òkè ní'dì,
Tó nmú àwọn odò nlá ṣàn,
Tó gb'áwọsánmọ̀ ró,
mf À nkọrin ọgbọ́n Ọlọ́run,
T'òrùn tó nràn lọ́sàn,
Oṣùpá mọ́lẹ̀ l'áṣẹ Rẹ̀,
Ìràwọ̀ bákan nà.

2. À nkọrin ṣe nlá Olúwa,
Tó m'ónjẹ kún ayé,
Ó dá'oun gbogbo pẹ̀l'ọ́rọ̀ Rẹ̀,
Ó wípé wọn dára,
Ìyanu Rẹ ti tóbi tó,
Gbogbo ojú sì nri,
Ní orí ilẹ̀ tí a nrìn,
Àti l'áwọsánmọ̀.

3. Àwọn 'odòdó àt'ewéko,
N'fògo Ọlọ́run hàn,
Ìkúkù àt'ìjì líle,
Wọ́n nsọ t'agbára Rẹ̀,
mf Gbogbo iṣẹ̀dá ọwọ́ Rẹ,
Ṣì nrí ìtọ́jú Rẹ,
Ibikíbi t'ówù kawà,
Ọlọ́run npẹ̀lú wa.

**JẸ́ KÓ BÀ LÉ MI**

1. Èlíjà lọ sókè Kármẹ́lì,
Kó f'òg'Ọlọ́run hàn,
Ní àkokò dánwò rẹ̀,
Pẹ̀lú wòlí bálì,
Èlíjà kan pẹpẹ kan,
Gbogbo ojú sì ri,
Jẹ́kí iná ọ̀run bàlé mi

Jẹ́k'íná bà lé mi (lẹ́ẹ̀mejì)
Iná Olúwa látọ̀run bàlé mi,
Agbára Ẹ̀mí Mímọ́,
Tó sọ̀kalẹ̀ ní Pẹ́ntíkọ́st
Jẹ́kí iná ọ̀run bàlé mi.

2. Ọgọ́fa ọkàn tó gbàgbọ́,
Lọ sí yàrá òkè,
Láti rágbár'Ọ́lọ́run,
Wọ́n gbàgbọ́ pé yóò sọ,
F'ọ́jọ́ mẹ́wà wọ́n ndúró,
Wọ́n ngbàdúrà kíkan,
Jẹ́kí iná ọ̀run bàlé mi.

3. A nílò agbára ọ̀run,
N'nú ọkàn wa lónì,
Láti tọ́ wa nrìn àjò,
Wa nínú ayé yì,
Olúwa rán iná ọ̀run,
Sọ́kàn ta rà padà,
Jẹ́kí iná ọ̀run bàlé mi.

## **ỌRỌ̀ AGBÁRA**

1. Gbogbo ibi gíga òkùnkùn, tí wọ́n yàn lòdì sí ìlera mi, Olúwa bá ọ wí lónìí, kú, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo ègún aìmọ̀dí tó n ró àwọn iṣòro mi lágbára, àrá Ọlọ́run yóò pa ọ́ run lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo àdéhùn tí sàtánì sagbátẹrù rẹ̀ pẹ̀lú ẹ̀mí ìkùnà, kú nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
4. Ẹ̀mí oògbé àti ìmẹ́lẹ́ nípa t'ẹ̀mí, àkokò rẹ dópin nínú ayé mi, jáde nípa iná báyìí, kú, ní orúkọ Jésù.
5. Olùba iṣẹ́-ìyanu jẹ́ ilé bàbá mi, olùba iṣẹ́-ìyanu jẹ́ ilé ìyá mi, látòní lọ, o kò tún ní ṣerere mọ́ nínú ayé mi, nítorínà, kú, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo òdù ilé bàbá mi, tí wọ́n yàn lòdì sí ògo ayànmọ́ mi, gb'iná báyìí, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ẹnu búburú tó n sọ̀rọ̀ ìkùnà sí àwọn iṣẹ́ ọwọ́ mi yóò gbẹ nípa iná lónìí, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**2 Sámúẹ́lì 22:2** Ó sì wípé, Olúwa li àpáta mi; àti odi mi, àti Olùgbàlà mi.

**2 Tẹssalóníkà 3:3** Ṣùgbọ́n olódodo li Olúwa, ẹnití yóò fi ẹsẹ̀ nyín múlẹ̀, tí yóò sì pa nyín mọ́ kúrò nínú ibi.

**Orin Dáfídì 34:17** Àwọn olódodo nké, Olúwa sì gbọ́, Ó sì yọ wọ́n jáde nínú ìṣẹ́ wọn gbogbo.

**Máttéù 10:1** Nígbàtì Ó sì pe àwọn ọmọ-ẹ̀yìn Rẹ̀ méjéjìlá sí ọ̀dọ̀. Ó fi agbára fún wọn lórí àwọn ẹ̀mí aìmọ́, láti ma lé wọn jáde àti láti ṣe ìwòsàn gbogbo àrùn àti gbogbo àìsàn.

**Orin Dáfídì 34:4** Èmi ṣe àfẹ́rí Olúwa, Ó sì gbóhùn mi; Ó sì gbà mí kúrò nínú gbogbo ìbẹ̀rù mi.

**2 Tímótéù 4:18** Olúwa yóò yọ mí kúrò nínú iṣẹ́ búburú gbogbo, yóò sì gbé mi dé inú ìjọba Rẹ̀ ọ̀run: ẹnití ògo wà fún láí àti láíláí. Àmín

**Ìsáíàh 41:10** Ìwọ má bẹ̀rù; nítorí mo wà pẹ̀lú rẹ, ma fòyà; nítorí èmi ni Ọlọ́run rẹ, èmi ó fún ọ ní okun; nítòótọ́, Èmi ó ràn ọ́ lọ́wọ́; nítòótọ́, Èmi ó fi ọwọ́ ọ̀tún òdodo mi gbé ọ sókè.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

## ÌJẸ́WỌ́ - ORIN DÁFÍDÌ 91

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo agbára òkùnkùn tí wọ́n yàn láti da ìrìn-àjò ayànmọ́ mi rú, mo gé ọ sọnù báyìí nípa iná, ní orúkọ Jésù.
4. Agbára àjèjì ìyówù, tó jókò sórí àga ayànmọ́ mi, ya wèrè, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
5. Olúwa, dìde nínú àánú Rẹ, máṣe jẹ́ kí àwọn ọ̀tá mi yọ̀ ayọ̀ lórí mi, ní orúkọ Jésù.
6. Olúwa, jẹ́ kí ìbínú Rẹ tú ìkórajọpọ̀ àwọn ẹlẹ́gàn ká, ní orúkọ Jésù.
7. Ọlọ́run, dìde, jẹ́ kí àgọ́ àwọn apẹ̀gàn mi wólulẹ̀, ní orúkọ Jésù.